Èṣù a maa wa ba ẹnikan ninu yin, yoo si sọ pe: Ta ni o ṣẹda èyí? Ta ni o ṣẹda èyí? Titi yoo fi sọ pé: Ta ni o ṣẹda Oluwa rẹ? Ti o ba ti ba a de ibẹyẹn, ki o yaa wa iṣọra pẹlu Ọlọhun ki o si jawọ

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i-: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: Èṣù a maa wa ba ẹnikan ninu yin, yoo si sọ pe: Ta ni o ṣẹda èyí? Ta ni o ṣẹda èyí? Titi yoo fi sọ pé: Ta ni o ṣẹda Oluwa rẹ? Ti o ba ti ba a de ibẹyẹn, ki o yaa wa iṣọra pẹlu Ọlọhun ki o si jawọ.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọrọ nipa iwosan ti o ṣe anfaani fun awọn ibeere ti èṣù fi n ko royiroyi ba olugbagbọ, Èṣù o maa sọ pé: Ta ni o ṣẹda eyi? Ta ni o ṣẹda eyi? Ta ni o ṣẹda sanmọ? Ta ni o ṣẹda ilẹ? Olugbagbọ yoo da a lohun ni ti ẹsin ati ti adamọ ati ti laakaye pẹlu ọrọ rẹ pé: Ọlọhun ni, Ṣùgbọ́n èṣù ko nii duro sibi aala yii ninu awọn royiroyi, bi ko ṣe pe yoo kúrò nibẹ titi yoo fi sọ pé: Ta ni o ṣẹda Oluwa rẹ? Nibi ìyẹn ni olugbagbọ ti maa da awọn royiroyi yii padà pẹlu awọn alamọri mẹta kan: Nini igbagbọ ninu Ọlọhun. Wiwa isọra pẹlu Ọlọhun kuro lọdọ èṣù. Kiko ara ro nibi titẹsiwaju pẹlu awọn royiroyi.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65013